# ELETI ỌFẸ

A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ...!

VOL. XIV NO 842 LAGOS SATURDAY OCTOBER 20 – OCTOBER 26 1962 KỌBỌ MEJI (2D)


## OJU A RI TO:

# Adajo Kotu Ju Oku Kan S'ewon Ni Pota

PORT-HARCOURT— Enmọ pẹlẹnbẹ, ọga awọn adajọ Kotu Ọlọpa Port-Harcourt, Ọgbẹni R. Dappa Wilcox ni a gbọ irohin ni ana wipe o sọ arufin kan ti orukọ rẹ njẹ Christopher Ogu, ẹni ọdun mejilelogoji ti o ku iku oro, sẹwọn ọdun meji nitoripe o jẹbi ẹsun ti awọn ọlọpa fi sun.

Bayi ni ọrọ na lọ: laipẹ yi ni ọwọ awọn Ọlọpa Port-Harcourt tẹ Ogu, ogboju ọlọṣa yi nibiti o gbe fẹ fọle Ọgbẹni kan ti nwọn npe ni Ijeoma Ogwu ni Diobu, nwọn si ba ibọn ati awọn irinṣẹ ti awọn ọlọṣa fi nfọle lọwọ rẹ.

(Wo yoku loju ewe kẹjọ)


### THE NATIONAL BANK Of Nigeria Limited

Incorporated in Nigeria in 1933
Paid up Capital £3,181,000

HEAD OFFICE
82/86, BROAD STREET, LAGOS NIGERIA.
Bankers to the Western Region Government of Nigeria

DIRECTORS:

SAMUEL LAYIWOLA DUROSARO–Chairman/Managing Director ABDUL AZEEZ OLAYIDE DUROSHOLA–General Manager AYOTUNDE OLATUNDE OSHINIBI

LONDON OFFICE
15,THROGMORTON AVENUE, E. C. 2.

Manager J. F. Burton.

Telephone London Wall 4303 — Cable & Telegr amsn Natbaniger ; Lon do.
Head Office Representative in London.

E. Akinwumi Doherty,

CORRESPONDENTS

NEW YORK PARIS HAMBURG
30 Branches Throughout Nigeria Including

IBADAN. BENNI-CITY. SAPELE. ABA. KANO. ZARIA. JOS.


## Nitori Nwon Da Ikan Duro:

# Awon Onise Moto Da Ise Sile Ni Ilu Oyinbo

DAGENHAM— Ni oru ijẹta mọjumọ ana ni awọn oṣiṣẹ ile mọto ti nwọn npe ni Ford Motors ni ilu Oyinbo binu da iṣẹ silẹ fun awọn onisẹ wọn, nwọn si tọwọ kuro ninu ile iṣẹ na nitori ẹnikan ti orukọ rẹ njẹ William Francis ti nwọn gbe'jo fun nibi iṣẹ moto na laipẹ yi.

(Wo yoku loju ewe kẹjọ)

## ILORIN ATI AWỌN IGOMINA PARAPO

**Oro Ijoba Ibile won di o r o Suru. Ka alaye Olofintoto Eleti-Ofe lori oro na ni oju ewe keta ati ikejo.**

FIAT 600 D

1 2 3 4

THE LITTLE 4 SEATER CAR

PRICES

| | Ex-Lagos | Ex-Turin |
|---|---|---|
| Saloon | £498 | £298 |
| Convertible | £540 | £310 |
| Multipla (4/5 Seater) | £630 | £365 |



LEVENTIS MOTORS LTD.

LAGOS (FB) IBADAN KADUNA KANO JOS PORT-HARCOURT ABA

# Ṣardauna Fi Aake Kori L'ori Ijoba Eko

KADUNA— Ọlọla Alhaji Amọdu Bello, Alakoso Ijọba Ipinlẹ Ariwa fi aake kọri lori ọrọ Ijọba Apapọṣe l'Eko ti awọn ọmọ ẹgbẹ Alaake (N.P.C) ati ẹgbẹ alakuọ (N.C. N.C.) jọ nṣe, o gbe ikede kan jade wipe nwọn nwa ija Ijọba on lori iwe adehun owo ṣiṣe ti awọn Ijọba Apapọṣe ni ki Oloye Okotie-Eboh fọwọ bọ pelu awọn ara ilu Israeli, awọn iran Ju (Jew) ni Jerusalẹmu.

Alhaji Amọdu Bello ni, ni ti on ati Ijọ awọn ni ilu Hau awọn ko ni ba awọ Oyinbo na lo, nkan ki nkan ti nwọn l ni lowo ati logbon Ọrọ na wa di talak ti o mba olowo sọ

## Ba Ko Daya

Okun nle, Aga yin ko wẹ. Mo gb wipe awọn ọm ẹgbẹ oṣelu Alaa (NPC) ti di BA K DAYA ni ilu E lori idibo si Minisifa ti nwọn ni Ekọ ni ọjọ ti o kọja Ọpọlọ pọ oko-ọrọ awọn ọmọ ẹgbẹ oṣelu Alaake (NPC ati ẹgbẹ Alaku ti nsọ si ara wọn lori iyọri si idibo na.

Awọn NPC ti ko ba si awọn ọmọ, ẹgb Alakukọ ko le r nkankan ṣe ni ar ilu Eko. Awọ N.C.N.C. ni ir ni nwọn npa.

# Oro Ilorin Pelu Awon Igbomina Di Oro Suru (2)

## (Lati Owo Olofintoto)

Gbogbo ẹnyin ọ kawe mi, mo ri wipe ẹ ka gbogbo nkan ti ọkan ninu awọn ọmọ Igbomina ti o nkọ ẹkọ ni ilu Oyinbo sọ ninu iwe Eleti-Ọfẹ ni ọsẹ ti o kọja nipa ọrọ awọn ara Ilọrin pẹlu awọn Igbomina ti nwọn ni ki awọn alamojuto Ijọba Ibilẹ ilu Ilọrin pin Ijọba Ibilẹ fun wọn ki awọn na le ri aye mu oju to gbogbo bi nkan ilọsiwaju yio se de ilu awọn.

Gẹgẹbi Olotu iwe irohin Eleti-Ọfẹ ti sọ wipe ki nṣe iwadi ọrọ na ti o ti di koko lati bi ọdun diẹ sẹhin, awọn agbalagba ni ẹnikan ki gbọn tan; mo si ro wipe ẹyin na a kan saara si mi gẹgẹbi OLOFINTOTO Eleti—Ọfẹ nibiti mo gbe wa ọrọ na de ki nto sọ wipe ọrọ na ti di ọrọ suru.

### Irepo

Nitotọ ko si Olowo kan ti o fẹ ki amusin on kuro lọdọ on, ṣugbọn mo mọ daju wipe awọn ara Ilọrin ko jẹ pe awọn ọmọ Igbomina ni ẹru awọn, ọkanna ni gbogbo wa, ija lode ni orin di owe.

Iwadi ọrọ mi na nko lẹ ki o mu ọrọ kunnu tabi ede aiyede wa fun ẹnikan. Eyi ti mo ba sọ ti ko yẹ nyin, ẹ le kọ iwe si Olotu Eleti-Ọfẹ fun alaye kikun lori ọrọ na.

Iwadi ọrọ Igbomina pẹlu Ilọrin na jẹ ẹlẹge tobẹgẹ ti awọn ọmọ Igbomina ti o wa l'Eko ki fẹ fesi ti a ba bi wọn lere wipe nibo ni wọn ba ọrọ na de.

Mo niran gbogbo igba ti mo npara ọdọ alaga awọn ọmọ ẹgbẹ Igbomina Parapọ l'Eko, Ọgbẹni David Ogundele ninu ile rẹ ni Oko-Awo. Alagba na ngba mi lọwọ lẹsẹ ṣugbọn ko nfun mi lọrọ kan ti mo le ri di mu ni pato lori ọrọ na.

Bẹ si ni akọwe ẹgbẹ na tiṣe Asoju awọn Igbomina ninu ile Igbimọ-nla Ijọba Apapọṣe, Ọgbẹni Ọlatunde. Mo para ile rẹ ni MAC—LEANE Road ni Yaba titi.

### KADUNA

Ni igbẹhin emi na wa ri wipe ki nti ẹsẹ bọ ṣokoto ki nlọ si Ilọrin ati Kaduna lati wadi ọrọ na ni ẹkunrẹrẹ ni o dara. Ni akoko ti mo de ilu Ọffa awọn kan ṣe ẹnu foro sọ fun mi wipe awọn oṣe'u kan npe awọn ijoye ati agbalagba ilu wipe ki nwọn tọwọ bọ iwe wipe awọn ko lọwọ ninu ọrọ ki nwọn pin ijọba ibilẹ fun awọn Igbomina ti nwọn npariwo ni Eko.

Nigbati mo de Oke Ajẹlẹ (Resident's Office) nwọn ji ọrọ sọ fun mi wipe ọpọlọpọ iwe-ẹbẹ ti awọn kan kọ lori ọrọ ipinlẹ ọtọ fun awọn Igbomina, ti nwọn fi ranṣẹ si awọn Ijọba Ipinlẹ Ariwa ni Kaduna ni nwọn ti da pada si Ajẹlẹ ni Ilọrin nitoripe gẹgẹbi eto ọdọ Ajẹlẹ Ilọrin ni awọn iwe-ẹbẹ yi kọ ni lati gba de ọdọ Minisita Alakoso Ijọba Ibilẹ ni Kaduna.

(Wo iyoku loju ewe kẹfa)

# Kabiyesi Oba Alake Ademola Keji (6)

## (Lati Owo Omo Abati)

(O bẹrẹ ni ọsẹ ti o kọja)

### OMINIRA EGBA

Gẹgẹbi mo ti sọ fun nyin nigbati mo ṣẹṣẹ bẹrẹ itan mi wipe nigbati awọn Oyinbo gọsi de ba awọn Ẹgba ninu idẹra ominira ni nwọn ba wọn.

Awọn agbalagba ologboni ni atiṣe ilu wa lọwọ. Awọn ologboni na si fi gbogbo nkan s'eto; nwọn ni ẹru lara.

Lẹhin ti Ọba Gbadebọ ti ti ilu Oyinbo de ni 1904 gbogbo nkan mere-mere ti o ri ti awọn Oyinbo ṣe si ilu wọn ni on na si fẹ ṣe si ilu Abẹokuta sugbọn gbogbo rẹ ọrọ owo ni ko si si Ijọba kan ti o le gbe ori laisi owo lọwọ. Ọrọ wa di wipe nwọn ni lati ṣe ofin ki awọn ara ilu ma san owo-ori fun Ijọba. wọn ki nwọn le ma ri nkan lo lati fi tun ilu ṣe.

Nkan ti ọrọ ogun Ijẹmọ da silẹ fun awọn Ẹgba ni nkan buruku pọ. Ogun yi sọ ọpọlọpọ di alaini baba. Ọrọ Ogun Ijẹmọ na ni o si fa Ijọba Ẹgba ti o ti jẹ Ọlanrewaju sẹhin. Nitoripe lẹhin ogun na ni awọn Ijọba Gẹsi gba ominira lọwọ awọn Ẹgba.

### OGUN ADUBI

Awọn lebira onisẹ ọba ko wọ pọ, bẹ Ijọba si ni lati lo enia lati tun ilu ṣe Eleyi si jẹ ki awọn ọlọpa ma mu awọn ara ilu ṣe iṣẹ apapandodo. Nwọn ko fi a nmu ni ṣe iṣẹ nipa yi mọ ni arin ilu nikan wọn tun gbe wahala na lọ ba awọn Ẹgba ni arọko

(Wo yoku loju ewe kẹfa)

PHILIPS
for RADIO
PHILIPS

# ELETI—OFE

ANJUWỌN KO ṢE WI LẸJO
EDITORIAL OFFICE & WORKS CABELS & TELGERAM
28 Kosọkọ Street, Lagos. "E.ETI—ỌFẸ" LAGOS
P. O. Box 468 Phone 23370
VOL XIV. No 842, SATURDAY. OCT. 20, – OCT 26, 1962


## E Ku Ajabo

Awọn Yoruba pa owe wipe "Oloye enia ni ọrọ mba wi"; ọrọ owe yi ni o ba nkan ti awa oniwe irohin Eleti-Ọfẹ fẹ ba gbogbo ẹnyin ara ati ọmọ Eko sọ lori idibo ti e di ninu ọsẹ yi fun awọn aṣoju ti ẹ yan sinu ile Igbimọ ibilẹ Eko ti ẹ npe ni Minisifa.

Ki a mase tan ara wa jẹ, idibo Ọmọluwabi ni idibo ti ọtẹ yi. Ko si ariwo a nṣe kanpeni ni bẹ.

### IFELODUN

Ọpọlọpọ ni iwe ti awa oniwe irohin Eleti—Ọfẹ ti ri gba lati ijẹfa lọdọ awọn ọkawe wa ti nwọn nsọ wipe ki a ba awọn dupẹ lọwọ gbogbo yin ti ẹ mọ wipe Olori ni o yẹ ki a fi ori fun.

Ko si olori kan ni ibikan ju wipe ki a ni ife si ara wa, ko ba ṣe Ibo lo jẹ tabi Hausa ni tabi Yoruba ni; Ifẹloju.

Oruko ti o yẹ ki awa ọmọ Nigeria lọkunrin, lobinrin ati ọmọde ati agba ki a mọ jẹ ni ọmọ ẹgbẹ Irẹpọ nitoripe ninu gbogbo awọn ara Ipinlẹ Iwọ Orun Africa (West Africa) awa ara Nigeria ni nwọn mọ ni olori. Ibiti a si pe lori a ki fi tẹlẹ.

Ti a ba mọ iru ọrọ-ko-ba-ikun-gbe ti awọn Oyinbo nsọ nipa wa wipe awọn kan ti nlu ida oloro lọwọ lati fi pa orilẹ awọn Yoruba danu kuro ninu awọn oṣelu, a o mọ wipe o yẹ ki a ni irẹpọ ki a ja fun awọn ọmọ wa ti nwọn mbọ lẹhin ọla ki nwọn mọ ṣẹ epe fun wa wipe a ti ba aiye jẹ fun awọn.

Abọ ọrọ ni a nsọ fun ọmọluwabi nitoripe ti o ba de inu rẹ a di odidi. Ṣọn ni a rin, aje ni muni pẹkọrọ.

Lẹkan si, a ki nyin, ẹnyin ọmọluwabi, ẹ ku 'ajabọ

## {Iwe Si Olotu}

### Ara Eko, Mo Gba Fun Nyin

Nwọn ni bi egungun ẹni ba mọ ijo jo ori a ma ya atọkun rẹ. Mo gba fun gbogbo ẹnyin obinrin Eko, Yaba ati Ebute-Mẹtta ti a kesi wipe ki ẹ fa ọmọ yọ, ki ẹ fi iṣẹ nyin silẹ ki ẹ dibo fun awọn ọmọluwabi ti ẹ si ṣe bẹ.

Gẹgẹbi mo ti sọ fun nyin wipe obinrin bi yin ni mi. Mo kan saara si nyin ti gbogbo yin ro ti ikunlẹ abiyamọ. Gbogbo ẹnyin ti ẹ ba jẹ ọmọ Yoruba le rin falala nisisiyi wipe ọmọ ọkọ niyin, ẹ si ni oriki. Owo tobi ni ko to enia rara.

Mo tun fi iwe kesi gbogbo ẹnyin abiyamọ ti o mbẹ ni Ipinlẹ Iwọ orun bi Abẹokuta Ibadan, Oyọ Oshogbo, Ilesha, Ogbomoshọ, Ekiti, Benin ati bẹbẹ lọ, ti ọjọ idibo ti yin paapa ba de ki ẹ fa ọmọ yọ, ki ẹ dibo fun OTITỌ. Otitọ ni yio leke nibikibi.

Oke Popo, Emi ni,
Eko Iyabọ Aya Lawale

### Owo Olowo Da?

Ẹ jọwọ ẹ ba wa bere lọwọ awọn alamọjuto Ijọba Apapọṣe wa l'Eko wipe kinni nwọn fẹ ṣe lori awọn onitẹtẹ pulu (pools) ti nwọn ko fẹ san owo fun ogunlọgọ awọn enia ti asọbade wọn lori tẹtẹ na wọle si rere.

A ṣe akiyesi pe niwọn oṣu kẹta lọhun ni awọn alamọjuto Ijọba wa gbe ofin kan jade lati fi wa lọkanbalẹ lori tẹtẹ-pulu ti a nta na, pe ẹnikẹni ti o ba ṣe orire ti nwọn ko ba san owo Oluwa rẹ fun awọn yio fi iya jẹ ọga ibiṣẹ na.

Eyi ti ijọba ba ṣe ninu ọrọ yi ni ao fi mọ iru Ijọba ti a ni, ṣugbọn ẹbẹ ni a mbẹ oṣika.

Ẹ ba wa gbaa lọwọ awọn Kọra ati awọn enia wa ti nwọn pa imọran pọ lati rẹwajẹ.

Ikorodu Rd, Emi ni,
Yaba A.Ladipọ




Aworan ọkunrin kan ọga awọn ṣọja Nigeria Brigadier J. Tu-Alrosi ni ẹnwo yi nilu Oyinbo ni biti o gbe nwo awọn moto ṣọja orişirişi ti nwọn nlo ni oju-oguu nibiti nwọn ko awọn moto nla-nla ra si ni ilu ti nwọn npe ni Chertsey. Adajọ moto bọlugi ni orişirişi ni nwọn ko sibẹ.

## E ka Irohin Ayiluka
### Loju ewe Karun

# Nihin Lohun Ati Nibi Gbogbo

(LATI ỌWỌ AYILUKA)

## Idibo Gaskia

Ṣe ẹnyin ọkawe mi niran nkan ti mo sọ fun ni ọsẹ ti o kọja nipa idibo wipe idibo ọtẹ yi ti awọn obinrin ẹlẹyinjuẹgẹ ni. Nitotọ awọn obinrin Eko ṣe gudugudu meje nibi idibo na. Awọn ti Yaba ni kilo ṣe awọn bẹni awọn ọmọ Isalẹ-Eko ati awọn ọmọ Olowogbowo. Mo ba gbogbo ẹnyin ara Eko yọ, ẹ ti fa ọmọ yọ.

Nwọn ni ibi ẹlẹkun gbe nsọkun ni alayọ n y ọ iyẹn ni ti iku arabinrin wa, Sikiratu Adunni aya Agbabiaka ọmọ ologbe Ayẹni ti o jalaisi ni owurọ ọjọ idibo. Baba o l o g b e na ṣe gudugudu meje fun awọn ọmọ ẹgbẹ Afẹnitẹre (AG) nigba aiye rẹ. "Senior" o digba o sẹ.




## Iyawo Dun

Nwọn ni bi ọmọ ba to lọkọ o yẹ ki o lọkọ. Mo ba Ayọ ọmọ Sangster ti o sẹsẹ lọ si ile ọkọ ninu ọsẹ ti o kọja yọ. Nkan ti ko ye mi ninu ọrọ na ni bonkẹlẹ ti nwọn ṣe iyawo na. Gbajumọ Ayọ pọ kosi yẹ ki a ṣe igbeyawo re ni bonkẹlẹ.

Boya bale rẹ tuntun na ti nwọn npe ni Dokita Austin Peters, ọga a w ọ n sọja onisegun, ni o ni on ko fẹ iyawo na ni alariwo nitoripe gbogbo alanu lo dọbalẹ a ko mọ eyiti anu nrun.

## Ọgun Adaja

Ọlọrun ki o gba wa l ọ w ọ ogun-adaja sugbọn bi ti ilu Kongo (Congo) kọ. Ninu oṣu ti o kọja yi g b o g b o awọn ọmọ Nigeria ti o wa ninu ilu na ni nwọn gbe ogun ti, ti nwọn nlu wọn ni alubolẹ, awọn ọlọpa Kongo na si dana sun nwọn nile wnọ tu wọn si ihoho nwọn si gba o wo ọwọ wọn.

Ọrọ re o, Ọgbẹni J a j a Wachuku, Minisita alamojuto ọrọ okere, eleyi ti kuro ni ọrọ k i a joko s i Ẹhingbeti ki a ma fọn enu lasan. A w ọ n a r a Kongo fẹ ko iyan wa kere, nwọn'sa tilẹ ti sọ wipe iso ni olokunrun fi dupẹ. Ju gbogbo rẹ lọ emi Ayiluka nwo eyiti awọn alakoso Ijọba yio ṣe lori ọrọ na.

## Oni–Pulu

Awọn onitẹtẹ Pulu (Pools) wọ gawu lọsẹ ti o kọja yi, gbogbo awọn ti nwọn ta tẹtẹ ti ori wọn wọle ni nwọn ko ri owo san fun wọn. Mo gbọ wipe awọn Minisita wa nro nkan ti awọn yio ṣe f u n wọn lọwọ. Boya ti Alhaji Usman Saki tiṣe minisita alamojuto ọrọ arin ilu ba de lati idalẹ a ro ọrọ na ṣe fun a w ọ n ara wa, ṣugbọn ọrọ awọn Kọra kanpa nwọn mọ orisirisi ọna lati la ena mọlẹ bi nkan ba dikoko bayi.

Mo gbọ wipe ẹkan ninu awọn Kọra onisẹ-tẹtẹ na ti fi ẹsẹ fẹ, o ti sa kuro nilu. Boya Kutọnu ni o lọ sapamọ si ko ye mi ṣugbọn mo mọ pe nkan mbẹ lẹhin ọrọ awọn Kọra onitẹtẹ na.

## Buredi Bolugi

Emi Ayiluka gbọ lati ẹnu awọn oni-burẹdi Eko wipe Ijọba ti kọwe ẹbẹ si wọn wipe awọn a ro ọrọ wọn lori fulawa, ki nwọn tete pada lọ ṣe burẹdi fun awọn ara Eko sugbọn awọn ara Eko ko fẹ burẹdi bọlugi rara.

## Ba Ko Daya

Ọlọla Amọdu Bello Alakoso Ijọba Ipinlẹ Ariwa ni awọn Alakoso Ijọba Ijọba Apapọṣe l'Eko nwa ija on nitoripe nwọn tẹ on loju mọlẹ Kinni o fa a ? Nipa ọrọ iwe adehun owo ṣiṣe ti Oloye Okotie-Eboh fọwọ bọ pẹlu awọn iran ti a npe ni Israẹli (Ju) ni Jerusalem ni o fa a.

# Kabiye Oba Alake Keji

( O bẹrẹ loju ewe kẹta )

Eleyi pelu owo-ori ti o je nkan ajoji fun awọn Ẹgba jẹki nwọn fi aake kori, o si jẹ ki ogun miran bẹ sile ni ọdun 1918, nwọn si pe ogun na ni Ogun Adubi.

Lẹhin ti nwon ti pari ogun Ijẹmọ yi ni awọn Ijọba Gẹsi ba gbe ofin kan jade wipe awọn ko gbọdọ ri ibọn "sakabula" ni ọwọ enikan mọ ni arin ilu Abẹokuta ati gbogbo aroko awọn Ẹgba. Eleyi mu wahala ba awọn agbẹ loko nitoripe ibọn sakabula yi ni nwọn nlo lati fi pa awọn ẹranko ti o mba wọn ni nkan ọgbin ti nwọn gbin si oko wọn jẹ.

Wahala yi ti awọn ọmọ Ẹgba, awọn bi Ologbe Pa J.K. Coker (ọmọ Ajọbọ) ati Ologbe lọya Eric Ọlawọlu Moore (Ọmọ Burada) dide si ọrọ na lọdọ Gomina ni Eko ki nwọn to yi ofin na pada lati ko ibọn oniibọn fun wọn.

Ariwo ogun Adubi le ju ti Ijẹmọlọ nitoipe awọn Ẹgba ti fi ake rkọri wipea ki i ku ni ..
na ni n
runwi nwon
a ti nwọn k

ni aroko. Bi nwọn ti nyin bọn sakabula si nwọn ni nwọn tun nfi ogun imajele ba wọn ja. Nwọn pa Oyinbo onisowo kan ni apafọn ni Tesan Wasinmi.


IBI IJOKO AWAMOTO INU AUSTIN S 200
DARA TOBE TO FI NMU ARE AWAMOTO
DINKU PUPOPUPO –
O NMU MOTO—WIWA RORUN PELU AISI EWU !



Moto Austin to ... si ... alekun ... ewu ... a ti ... dara ... ojiji ... Moto S ati T 200 ... bale fun ọru kiko; ... lagbara, ... ẹhinrin ... ewu. Bere pe ki a wa ... ki o ri i.

Head Office 237 — 241 Igbosere Road, ... Lagos. Garages at Aba, ... Ibadan, Jos, Kano, Lagos ... Port Harcourt.

AUSTIN S 200

SCOA Motors


## Oro Ilorin

(O bẹrẹ loju ewe kẹta)

### Kayefi

Nigbati ina ọrọ ipinlẹ ọtọ fun awọn Igbomina na njo lemọ-lemọ ni ile ati lẹhin odi, "kayefi" ni ọrọ na jẹ fun Ọlọla Amodu Bello, Srdauna Sokoto ti on na fi pe awọn Oludamọran rẹ jọ lati ji oro lori rẹ. Mo gbọ wipe nwọn kan Ọgbẹni A.O. Ọlarewaju tiṣe Minisita ninu Ijọba Apapọṣe, l'Eko lara lori ọrọ na lati gbọ ti ẹnu rẹ.

Ninu ipade pataki ti nwọn ṣe na ni Kaduna lori ọrọ kayefi ti awọn ara Igbomina na, nwọn pe Alhaji Sardu Alanamu (tiṣe Asoju ni ilu Oyinbo) ki o to lọ si ilu Oyinbo sibẹ ati Minisita alakoso nkan ọgbin, Mallam Ọkin ati awọn aṣoju Ọba Ilorin, Mallam Sulu Gambari. Nwọn si jiroro nkan ti awọn le ṣe lori ọrọ na ti irẹpọ a fi wa larin awọn Ijọba ibilẹ Ilorin pẹlu awọn ara Ọffa, Igbomina, Oke-Ọdẹ, Ekiti ati Ibọlọ.

Lẹhin ipade yi nwọn wa ri wipe o yẹ ki awọn ran Alhaji Sule Gaya tiṣe Minisita Alamojuto Ijọba Ibilẹ ni Ipinlẹ Ariwa lọ si Ilọrin ati agbegbe rẹ lati lọ ṣe alaye nkan ti awọn Alakoso Ijọba ro lori ọrọ na fun gbogbo awọn ara Ilọrin ati awọn ọmọ Igbomina.

Ẹda ọrọ ti Alhaji Sule Gaya sọ lori ọrọ na ti mo gba ni Kaduna mu lẹ ẹ jade fun nyin ninu iwe irohin Eleti-Ọfẹ ti ọsẹ ti mbọ. Ki fi pamọ nitori o le di ...en iian lọjọ ọla.

(Koi ti pari)


E polowo
Oja yin sinu iwe irohin Eleti-Ofe Losose

## New Transport For Farming Countries

# Hovercraft Can Travel Air, Water And Land

LONDON — A new development in transport, the vehicle that is neither bus, or aircraft, nor boat, but something of all three, will be described in the BBC series IN CONSTANT TOUGH, on Wednesday next.

Called the Hovercraft, this British invention can travel either on water or over land-and over land and water of any kind: swamp, desert or river, it is all the same to the Hovercraft, since it rides on a cushion on air just above the surface.

The Hovercraft is no more scientific curiosity either. It has already gone into puplic service in the north-west of England, where Hovercraft cross a wide and silted river estuary six times a day.

The Hovercraft has tremendous possibilities for vast areas in the new countries of Africa. For instance there is a truck with Hovercraft adaption that makes it possible to journey over boggy ground or muddy ploughed land, places where an ordinary truck would come to a complete standstill. And the Hover Truck is specially useful for spraying or dusting crops with fertilisers and insecticides where ordinary trucks cannot drive and on ground that cannot be reached by crop-spraying aeroplanes.

In next Wednesday's BBC programme which is part of a monthly series IN CONSTANT TOUCH, listeners can hear more about this latest weapon in the farmers battle bad weather.

# Hovercraft After Demonstration



**Britain's Hovercraft comes ashore on Osborne Beach after a recent demonstration on the Solent. This passenger craft can carry 66 passengers and baggage or 8 tons of freight and has a range of 260 nautical miles at 80 knots.**

## Nigerian Works in British Factory

LONDON — W[illegible] no training at the [illegible]us Brush Electrical Engineering in Loughborough has proved and "exciting" experience for 22-year-old Nigerian student Harrison Adedotun Plumptre, of Upper Ofin Lane Lagos for he has been working on important equipment destined for West Africa.

Brush Electric is showing some of its equipment in the British Pavilion of the Nigerian International Trade Fair.

"During my first year I worked on switch gear being manufactured at Brush for the Eastern Region Ministry of Works, and on transformers for the Tema hydro-electric scheme in Ghana," he told an L.P.S. correspondent yesterday.

"One of my most exciting experience has been working on the 'Falcon' diesel electric locomotive one of the finest in the world".

Mr. Plumptre spends three days a week doing practical work at the Brush factory, and two day's study at the Loughborough College of Further Education, where he hopes to do physics and mathematics at advanced G.C.E. level as well as his O.N.C. in electrical engineering. Later he hopes to go on to the Loughborough College of Advanced Technology.

Mr. Plumptre hopes to work with Eastern Nigeria's Electricity Corporation or with one of the generating boards when he returns.

# Ironin Soki

(LATI ỌWỌ AYILUKA)

Mo gbọ wipe awọn ọmọ Eko ti nwọn da ẹgbẹ kan ti nwọn npe ni Ẹgbẹ T'Ọba Laṣe (Lagos Royalists) silẹ fẹ ṣe bẹbẹ ni ọjọ Aiku (Sunday) ọla fun ọkan ninu awọn baba'salẹ wọn, Oloye Iṣhọla Jiyabi Keji, Eletu Odibo, nipa aṣeyẹ iwuye. Olofintoto mi fiye mi wipe gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ na lọkunrin ati lobinrin ni nwọn ti da aṣọ ẹgbẹ-jọda ti a npe ni aṣọ ẹbi ni Eko.

Awọn ọdọmọde inu ẹgbẹ na ni lati oni ọjọ Abameta (Satide) ni awọn yio ti bẹrẹ ṣiṣe aṣeyẹ iwuye na nitoripe awọn fẹ fi ijo bẹ ni alarẹnrẹn lati oru Satide na mọju ọjọ Aiku (Sunday) pẹlu awọn iyawo'le ati awọn ọlọmọge iyawo'ọna.

Oloye Fagbemi Ajanaku Kẹta, Araba Eko tiṣe igba-keji baba—ẹgbẹ ati akapo ẹgbẹ na ati akọwe ẹgbẹ na, Ọgbẹni J.B. Macaulay wọn a ṣe gudugudu meje nibi iwuye na. Nwọn ti fi iwe pe ọpọlọpọ awọn Oloye ati gbajumọ Eko si ibi iwuye na.

## Oyinbo Russia

Awọn Oyinbo ajoji kan ti nwọn ṣẹṣẹ de si arin wa ti a npe orukọ wọn ni Rọṣia (Russia) ti fun awọn ọmọ wa mẹrindinlogun ni ẹbun ẹkọ-ọfẹ lati lọ si ilu wọn ni Moscow fun ẹkọ ijinlẹ ti ti ile-waya, ẹrọ manana, ẹrọ olugbohun ati awọn nkan bẹbẹ.

Awọn mẹjọ ninu awọn mẹrindinlogun na ti tẹkọ leti ni ijẹta lati lọ si ilu awọn Oyinbo Rọṣia (Rossia) na.

Awọn ka ninu awọn Alamojuto Ijọba wa ti fi igba kan wipe awọn ko ni ba awọn Oyinbo ajeji yi ṣe rara, boya nwọn ti tun ọrọ na ro ni, ko ye wa rara, ṣugbọn a gbọ wipe awọn Oyinbo ajoji na rin jinna pupọ ninu nkan ijinlẹ ti o le mu nkan rere ba awọn araiye.

## Kosoko Jare Ejo

Laipẹ yi ni Adajọ Kotunla kan da Oloye Aminu Kọsọkọ, Asajọn Ereko, lare ẹjọ ti awọn kan ninu ẹbi rẹ, awọn John Aderẹmi Dungba Kọsọkọ pẹlu awọn meji kan pee nipa ile kan ti nwọn ti fi igba kan gba rẹnti adọta ọdun lọwọ Kọra ti o kọ ile si ori ilẹ awọn Oloye Kọsọkọ. Adajọ ti o da ẹjọ na ni on gba wipe ile-ẹbi ni, Oloye Kọsọkọ gẹgẹbi olori ẹbi Kọsọkọ ni o ni ẹtọ lori ilẹ na, atipe nwọn ti gba idajọ lori ilẹ ẹbi na ni iwọn ọdun kẹrindinlọgbọn (1936) sẹhin.

Adajọ ti o da ẹjọ na ti fi gege ge ọrọ na, o ni ki Ọgbẹni John Aderẹmi Dungba Kọsọkọ pẹlu awọn alatilẹhin rẹ lọ san pọnun marunlelọgọrun owo irin ẹsẹ (£105) fun Oloye Amini Kọsọkọ ni kia mọsa.

## Awon Oniburedi

Awọn Oniburẹdi ilu Eko ti nwọn fi igba kan taku wipe awọn ko ṣe burẹdi mọ ti bẹrẹsi ta burẹdi wọn ni ijẹta sugbọn nwọn ni kiṣe ọrọ ara isanwo burẹdi mọ nitoripe awọn Alamojuto Ijọba wa ti bu owo lori fulawa (flour) ti awọn fi nṣe burẹdi.

Iyẹn nipe a nra burẹdi ni awin ko si nibi kan rara mọ.

## Minisita Aganyin

Alakoso Ijọba Ilu Aganyin, Dokita Kwame Nkrumah ti tun gbe omiran de si awọn Minisita Alamojuto ile iṣẹ Ijọba ilu rẹ. O ni on fẹ yan awọn Oluwadi ti yio ṣe iwadi ẹnkuari gbogbo ile iṣẹ wọn lati ajọda-iṣẹ de ibi iṣẹ kekeke.

O ni awọn enia mẹrin pataki ni yio ṣe iwadi ẹnkuari na ṣugbọn Ọgbẹni Emanuel Ayeh—Kumi ni yio ṣe alaga iwadi na nitoripe awọn fẹ ki gbogbo awọn ara ilu ri pe awọn ko na owo ilu na lọna ti ko tọ ati pe awọn ko ṣe ọlẹ lẹnu iṣẹ Ijọba.

## Igbimo Minisifa

Akọwe ile iṣẹ Minisifa Eko, Ọgbẹni Mayaki ti fi iwe ikede sode wipe gbogbo awọn aṣoju ti nwọn fi idibo yan sile igbimọ Minisifa ni awọn ti kesi wipe ki nwọn wa si ipade igbimọ na ni ọtunla ọjọ Aje lati wa yan Alaga fun ijoko wọn.

O ni irọ ni nwọn npa wipe ẹnikan ti di kọkọrọ-ile igbimọ na mọ ọwọ. Gbogbo awọn ti nwọn fi idibo yan ni nwọn ti tẹ orukọ wọn sinn iwe Ijọba ti nwọn npe ni Geṣẹti (Gazette).

---

## Adajo Kotu

(O bẹrẹ loju ewe kini)

Lẹhinti ọwọ awọn ọlọpa tẹ ẹ, ti nwọn de ile rẹ nwọn ba oriṣiriṣi ẹru ole ti nwọn ti nwa lọdọ rẹ.

Ni ẹnu wipe nwọn nṣe ẹjọ rẹ lọwọ ni o ri ẹnikan duro fun, ṣugbọn dipo ki ogboju ole yi joko rẹ jẹ nṣe ni o tun di ara, ti o mura ọlọṣa ti o gba ilu Owerri lọ lati lọ ko wọn nile. Nibiti o ti nko wọn nile ni awọn onile taji ni nwọn da a ni ahaya ọta ibọn ti o ṣubu lulẹ ti o si ku bamubamu.

Awọn iyawo ati alabagbe rẹ ni oni kọ ni awọn ti nsọ fun wipe ki o jawọ ninu iṣẹ ọlọṣa nitoripe iṣẹ na kiṣe iṣẹ ọmọluwabi.

Ni owurọ ọjọ ti adajọ ni ki o wa gba idajọ rẹ ni adajọ ri waya gba pe wọn ti yinbọ pa a ni Owerri loni nibiti o gbe tun lọ jale.

---

## Awon Onise Moto

(O bẹrẹ loju ewe kini)

Onirohin wa sọ fun wa wipe awọn oṣiṣẹ ile iṣẹ yi ti nwọn le ni ẹgbaa-mẹrin-dinlogun enia ti wa lẹnu rogbodiyan a-fẹ-da-iṣẹ-silẹ yi to ọsẹ mẹta, ṣugbọn nigbati awọn Oyinbo oniṣẹ ile mọto na ri wipe awọn oṣiṣẹ wọn na fi aake kọri wipe dandan awọn ni lati da iṣẹ silẹ, nwọn pe gbogbo awọn ọga awọn oṣiṣẹ na lati fi owo kun owo iṣẹ wọn.

Nwọn fun ẹnikọkan wọn ni ẹkunwo sile mẹwa mẹwa ni ọsọsẹ mọ iye ti nwọn ti nsan fun wọn, nwọn si pe ẹkunwo na ni owo ijapari.

Awọn ọga ti o ni ile iṣẹ mọto na ni ko tilẹ si nkan ti o dun awọn bi aṣẹ ti awọn ṣẹṣẹ ri gba lati ọdọ awọn onibara awọn wipe awọn fẹ ra mọto Olowo iyebiye (£15 million) ni kiakia lọwọ wọn.

Ọrọ wọn na koi ti pari di igba ti a ri waya irohin yi gba lati ilu Oyinbo.

---

## Gomina Lo Si Ilorin Ko De Oro

ILỌRIN—Ọrọ Gomina Ipinlẹ Ariwa, Ọlọla Kashim Ibrahim ti o lọ ṣe abẹwo awọn ilu ti o wa ni ipinlẹ ijọba rẹ, ti o de Ilọrin ti ko fi ẹsẹ kan de ọdọ awọn ilu ti a npe ni Igbomina ati Ekiti ti fẹ da rukẹ-rudo silẹ larin awọn ọmọ Igbomina nitoripe ọrọ na dabi ẹnipe "nwọn ko ka wa kun," bẹni awọn oguna gbongbo ọmọ ilu na ro si.

Onirohin wa ni lọjọ ti awọn ọmọ Igbomina ti gbọ wipe Gomina yi mbọ wa si agbegbe wọn ni inu wọn ti ndun wipe awọn a ṣe bẹbẹ fun un, awọn a si ri ọna tu nkan ti o ndun wọn lọkan fun un nitoripe awọn nfe ilọsiwaju fun ilu awọn kiṣe wipe awọn mba Ijọba Ibilẹ Ilọrin ja rara.

---

Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company. 28 Kosoko Street Lagos Box 467 Phone 23370 EDITOR (OLOTU): OLA ONA TAD
15, Kosoko Street Lagos.